## IPA ÒÒGÙN YÍ

Misoprostol nṣiṣẹ lati ba oyún jẹ lai nilo itọju ètò-ìlera míràn láàrin obìnrin mẹjọ ninu obìnrin mẹwaa.

## BÍ ÒÒGÙN NÁÀ KÒ BÁ ṢIṢẸ

Tún oyún ṣiṣẹ yi ṣe nípa tí tún òògùn Misoprostol lò tàbí nipa ètò-ìlera aláfọwọyọ nííléˌìwòsàn. Ewu díẹ wa ninu ọmọ-bibi pẹlu àléébù ti oyún náà bá tẹsiwaju lẹyin lilo òògùn Misoprostol.

## ṢE OYÚN ṢIṢẸ MI YEGE?

Bí obìnrin bá rò wípé oun ko ni oyún mọ, ó ṣe pàtàkì kíó rí i dájú pé oyún ṣiṣẹ naa ṣe àseyege. Obìnrin ni lati ṣe àyẹwò skanni lẹyin oyún ṣiṣẹ tàbí kíó ṣe àyẹwo oyún lẹyin ọsẹ kẹta si ikẹrin lẹyin oyún ṣiṣẹ naa.

## LẸYIN OYÚN ṢIṢẸ

Lẹyin oyún ṣiṣẹ, obìnrin ní lati retí dídà ẹjẹ díẹdíẹ fún ọsẹ kan sí mẹta, sùgbọn onírúurú obìnrin ni o wa. Lẹyin naa, obìnrin ní láti rí i dájú pé oyún ṣiṣẹ yii ṣe àṣeyege.

Imọran fún obìnrin ni pé kíó ma ṣe fi nkankan si ojú-ara bi (tamponu), wiwẹ tabi ìbálòpọ tító tí púpọ ẹjẹ dídà yio fi dúró bii ọjọ meji lẹyin ètò-ìlera oyún ṣiṣẹ.

**Obìnrin ṣile lóyún lẹṣẹkẹṣẹ lẹyin oyún ṣiṣẹ.**

Tí kò bá fẹ lóyún lẹṣẹkẹṣẹ, o le bẹẹrẹ òògùn idaabobo magboyun fun oyún  ti o kò fẹ.

## CONTACTS

Women Help Women
WEB: HTTPS://WOMENHELP.ORG/
EMAIL: INFO@WOMENHELP.ORG
TWITTER:@WOMENHELPORG
FACEBOOK: WOMENHELPWOMENINTERNATIONAL

MAMA Network: **Mobilizing Activists around Medical Abortion (MAMA).**
WEB: WWW.MAMANETWORK.ORG

# ÈTÒ-ÌLERA OYÚN ṢIṢẸ

PẸLU ÒÒGÙN MISOPROSTOL



## MISOPROSTOL, Kínni?

O jẹ oògùn lìló ní gbogbo àgbáyé tó máa ńṣẹ oyún pẹlu ati itọju ọgbẹ inú, o wa fún títà ni àwọn ilé-ìtajà Oògùn Òyìnbó ti o gba Ìwé-ẹri labẹ orukọ Sitotẹẹki, Isofẹnti, misoklẹr, misofemu, sirusi, tàbí Tomisipra. Ní púpọ ilẹ adúláwọ ni a tibu ọwọ-luwe lati fi tọju ati lati dènà ẹjẹ dida ti o pọju lẹhin ọmọbibi.

women help women

MAMA

# MISOPROSTOL,

## KÍNNI A LẸ LÒ Ó FÚN?

Oyún ṣiṣẹ láìlewu.

Lẹyin oyun tó bàjẹ́ tabi itọju oyún ṣiṣẹ (lati ṣe àsepé oyún ṣiṣẹ). dídènà ati itọju (ẹjẹ-dida pupọ lẹyin ibimọ).

o tun wa fun itọju ọgbẹ inú.

## BÁWO NÍ Ó ṢE NṢIṢẸ?

Misoprotol máa ńṣiṣẹ bakanna ni ìlànà oyún tóbàjẹ́ lára. Ó maa nje ki ọna ilé-ọmọ kó là kó si rọ, yio jẹ ki ile-ọmọ naa fúnpọ dáradára lati jẹ ki oyún náà wale

## NÍ GBÀWO NI A LÈ LÒÓ FÚN OYÚN ṢIṢẸ LÁÌLEWU

Ni ọsẹ kẹsan ti oyún ti dúró; kíká lati ọjọ akọkọ ti a ti bẹrẹ ǹkan osù tókẹhìn.

Lẹhin ọsẹ kẹsan, a gba ni imọran ka lo o labẹ awọn Elétò-ìlera Òyìnbó.

## BÁWONI A ṢE LÈ LÒÓ FÚN OYÚN ṢIṢẸ LÁÌLEWU

Obinrin nílo ẹyọ oògùn yii méjìlá lápàpọ lati lo ẹyọ mẹrin-mẹrin lẹẹ mẹta laarin wákàtí mẹta-mẹta sí ara wọn.

3h

Fi mẹrin oògùn Misoprostol si abẹ ahọn

30 min Fún ọgbọn iṣeju

Máṣe gbée mì, jẹ kíó yòrò

3h

Lẹyin wákàtí mẹta, fi mẹrin miran si abẹ ahọn fun ọgbọn iṣeju

30 min Fún ọgbọn iṣeju

Máṣe gbée mì, jẹ kíó yòrò

3h

Lẹyin wákàtí mẹta, fi mẹrin míran si abẹ ahọn fun ọgbọn ìṣeju

30 min Fún ọgbọn iṣeju

Máṣe gbée mì, jẹ kíó yòrò

## KÍNNI KÍÁ MÁA RETÍ LẸYÌN LÍLÒ OOGUN YII?

Inú-lilọ àti ẹjẹ-dídà láti óju-ara ti o lágbára jù ìgbà tí a ńṣe nnkan osù lọ.

24h Ní ìdá-ọgọrin, wiwalẹ oyun máa n ṣẹlẹ laarin wákàti mẹrinlelogun.

Bi oyún ba ṣe pẹ si, ni ẹjẹ dídà àti inú-lílọ náà ṣe ma n lágbára si.

O lè lo òògùn Ibrofeni tabi panadol lati dín ìrora náà kù.



## ÌPALÁRA TÍ Ó LÈ ṢẸLẸ

24h

Laarin wakati mẹrinlelogun, awọn amin wọnyii le fara han: Bi ririn nkan, Ẹebi, Igbẹ yiya sooro, Ara-gbígbóna tóní tabi tíkòni òtútú, Ori fifọ, pẹlu / tabi òòyi oju. Àwọn àmìn wọnyí kò léwu rárá, wọn yíò lọ láàrín wákàtí diẹ

## KÍNNI AWỌN AMIN IKILỌ (ÌDÀRÚ DÀPỌ)

Púpọ ẹjẹ Dida (meji tabi mẹta páàdì tó kún láàrín wákàtí kan ju wákàtímeji si mẹta léralera). 2h+

39° Ara gbígbóná (tíó ju ọkandinlogoji iwọn sensọọsi) tàbí ejidinlogoji iwọn sensọọsi tó koja wákàtí mẹrinlelogun. 24h+

Ìrora tí o lágbára tí kò si lọ lẹhin tí a ti lo òògùn Ìrora àti lẹhin ọjọ diẹ ti a ti lo òògùn naa.

Ririn, ajoji dida nkan lati oju ara obinrin.

## KÍNNI A LÈ ṢE BÍ A BÁ NÍÌDÀRÚ DAPỌ

**Lọ lẹṣẹkẹṣẹ si Ilé-ìwòsàn Ìjọba.**

Tí ó bá jẹ ètò-ìlera pàjáwìrì, Òṣìṣẹ Eto-ilera ni ojuṣe lati da eniyan lohun ni asiko.

Itọju idaru dapọ jẹ bakanna pẹlu idaru-dapọ oyun to bajẹ. Ko ṣeese lati ri iyatọ laarin oyún tó bàjẹ àti oyún ṣiṣẹ pẹlu òògùn Misoprostol. Obìnrin ti o nilo ètò-ìlera ìtọju le sọ wipe oyún oun bajẹ.